TI ẸDA NI IMỌ




Ọna ti o le fi ni imọ, Tito le fi mọ gbogbo ohun ijinlẹ nipa ẹda eyiti yio ma a ṣe anfani fun ẹ lojojumọ. Ti wa a fi ni Ilera, ọrọ, inudidun, orire, ati bẹẹ lọ. Ki o le mọ nipa ofin ẹda, wa wọ "ẸGBẸ ANCIENT KURAJEEH WHITE BROTHERHOOD LODGE" a fi ẹsẹ rẹ le ọna titun na. A ni orisirisi iwe adura ati ti imọ ijinlẹ nipa ẹmi, ẹ kọwe bere alaye kikun ki ẹ si fi sisi (6d) si i si:—
THE ANCIENT KURAJEEH WHITE BROTHERHOOD LODGE
52B Clifford Street Ebute-Metta, LAGOS

## KO SI ABAWỌN KAN LARA MI



MENTHOLATUM



"Mentholatum" Fiffpara a ma mu ki ara ọmọde ko ma ni abawọn, o rọrun pupọ lati lo. Lẹhin ti a ba wẹ ọmọ tan ki a fọra fi "Mentholatum" pa a lara ati yika ẹsẹ rẹ mejeji. Eyi ko ni jẹki ara ọmọ o ni isaka ati egbo, awọn ọmọde fẹran igbadun ati itura ti "Mentholatum" i ma a mu wa, tete lọ ra idẹ kan tabi agolo kan loni.
Bere fun Mentholatum gan an. Eyiti o jẹ pe awọn Mentholatum Co. Ltd., (Est. 1819) Slough, England nikan ni wọn ṣe e.

## IKỌ LEWU




Nigbakugba ti o ba wukọ inira ni o je fun ifun rẹ, okan re yio si ṣiṣẹ kọja ala. Lo VENO'S COUGH MIXTURE lati da ikọ rẹ duro! Egbogi pataki yi ni gbogbo aiye mọ, o nda ikọ duro, o njẹ ki mimi rọrun, o mu ọgbẹ ọna ọfun kuro, o si ntọju ifun daradara.

Ra igo kan nisisiyi!

Egbogi to gbọ orisirisi ikọ, orisirisi otutu ti iṣe agba tabi ọmọde.

VENO'S
LIGHTNING
COUGH MIXTURE

## J. A. Ajao & Brothers

GENERAL MERCHANTS
10, Egerton Road, Lagos, Nigeria

A nta awọn nkan wọnyi— Iṣana orisirisi (Matches), Oogun Iyagbẹ, Epsom Salt), Kafura Pẹlẹbẹ (Camphor), Atike (Face Powder), Omi Didun (Mineral Water), Cement, Bata Funfun (White Canvas Shoes Leather Shoes (orisirisi), Beer, Shnapps. Gin, Wine, Brandy.

## Medicine Stores

A tun nta awọn orisirisi ogun ni oke Ṣọbu wa — Oogun Narun Iba, Atun-ẹjẹ-ṣe, Ikọ, Jẹdi-jẹdi, ati ogun fun Obinrin ati Okunrin Lakuregbe, Ebia Ọmọde.

### DANIEL AKỌMỌLAFẸ ṢE IKOMỌ

KOTON-KARIFI LỌNA LỌKỌJA—Irohin ko to amojuba ni inawo Ọgbẹni Daniel Akọmọlafẹ lati igbati iyawo rẹ Ọlayẹmi ti bi ọmọ kunrin kan fun un ni ọjọ kejila oṣu kẹwa ọdun yi titi o fidi ọjọ ikomọ ni onjẹ ati ọti fi nrọ jọ.

Nigbati o tun di ọjọ keje ti iṣe ọjọ ikomọ na, lati arọ titi di alẹ ni baba ọmọ na fi ngbawo bi ẹlẹda, Alufa E. O. Ọladimeji ni o sọ ọmọ na ni Ọmọbọlaji. Ọgbẹni P. Ojodomọ ni o ṣe adura.

Diẹ ninu awọn ti o wa si ibẹ ni Ọgbẹni J. O. Adekunle, J. J. Martins, S. O. Fanumi, J. O. Ọlatunji, S. A. Aderounmu ati J. O. Ademuyiwa, ki Oluwa fi ire kario.

### IKOMỌ AMOS MIRINGINDIN

Tamale N. T. Gold Coast— Ni ọjọ Ajọ ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu kẹwa ọdun yi ni Ọgbẹni Amos Ọdẹbunmi ṣe ikomọ ọkunrin kan ti Ọlọrun fi ta on ati Iyawo rẹ Esther Ọdẹbunmi lọrẹ. Nwọn sọ ọmọ na ni Simeon Olufemi Ọdẹbunmi. Baba ọmọ na ati Iya rẹ si fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabapẹ lọrun.

Diẹ ti ayọ wa fun ninu awọn ti o wa si ibi ikomọ na ni:— Ọgbẹni Z. D. Ajibi, Amos Adigun, M.O. Affin, I.O. Oluwo, Z Ajayi, A.O. Alabi, John Oyinwọla, Ezikiah Arẹmu, Burimoh Parakoyi ati Marufu Ayilara. Ire a kari o.

E ma a polowo Ọja nyin sinu iwe

"IROHIN YORUBA"

Ẹ o si ri iyatọ larin bi ẹ ti ti ni onibara si ati bi ẹ o ti tun bẹrẹ si ti ni si lati isisiyi lọ.

